Bibeli fun awon omode



# Eniyan ina (Eniyan Onina)

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: E. Frischbutter

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Gbogbo nnkan kose daadaa fun Isreli. Oba kunrin ati oba binrin korira Olorun. Iru apeere buburu wo leyii, Nigbati o ya awon eniyan korira Olorun won si bere si sin Olorun eke. Se eni kankan nife Olorun? Beeni, Awon eniyan die si n sin Olorun lotito. Ni ojo kan,



Olorun ba okan ninu won soro oruko eni ti n je Elijah.

Elisa so fun Oba Abiabu buburu "Gege bi Oluwa Olorun Isreli ti mbe, ki yoo si iri tabi ojo ni Odun wonyii, ayafi oro mi." Eyi nni ni iyan! Olorun ko ni gba ki awon eniyan Isreli ma tesiwaju ninu iwa buburu won.





Leyin ikilo fun Oba, Olorun ran Elijah lo si ibikan didake roro ninu orile ede. Nibe, leba odo, Elijah duro, Olorun ran eye iwo lati maa boo. Won gbe akara ati eran, ni aaro ati ni ale. Elijah si mu omi ninu odo.



Laipe odo naa gbe, nitori ko si ojo ni ile naa. Oro Oluwa siwa si imuse. Ko si si omi ni ile naa. Koriko ko dagba. Ebi npa awon eniyan, lojiji Elijah nwo ohun ti yoo sele sii nisinsinyi ti ko si omi.

Olorun so fun Elijah "Dide, lo si Sarefati, ki o maa gbe ibe. Wo, mo ti pase fun obinrin opo kan lati maa boo." Olorun mo iranse re, sugbon o ngba ona iyanu lati pese. pelu irele Elijah gboran si Olorun. Nigbati o de Sarefati, o ba obinrin



opo kan ni enu ibode ilu n sa igi ti yoo fi dana jo.

"Jowo bu omi fun mi mu," Elijah beere lowo obinrin naa. "Jowo mu okele ounje die fun mi." "Emi ko ni akara," opo naa daa lohun. "Ikunwo iyefun ninu ikoko ati ororo die ninu kolobo."



Pelu ibanuje, obinrin naa so fun woli pe ti eyi ba ti tan, ki ebi si pa oun ati omore ku.

“Ma beru, tete ko se kekere temi na, leyin re ki o se tire ati ti omo re.” Elijah so bee. Iyefun re ko nii gbe, beeni kolobo ororo re konii tan titi di ojo ti Oluwa yoo ro ojo sori ile Olorun yoo se ise iyanu ki eyi le sele. O si see! Obinrin yii ati omo re je fun ojo pipo, sibe ikoko iyefun re ko sofo, beeni kolobo ororo ko sigbe.





Elijah ngbe lodo won, lojo kan isele buburu kan sele, omo obinrin opo yii ku. Elijah gbe omo naa lo si yara oke. O kigbe pe Oluwa wipe "OLUWA Olorun mi mo gbadura, je ki emi omode yii pada wa sinu re." Wo iru adura ti ko rorun?

Oluwa gbo adura Elijah, emi omo naa si pada sinu re, o si soji. Nigbati Elijah gbe omo naa le iya re lowo, o si wi pe, "Nisinsinyi mo mo pe oro OLUWA ni enu re otito ni."



Leyin Odun meta, Olorun ran Elijah si oba wi pe “Emi o ro ojo sori ile.” Lo ba Ahabu, iyawo re ti pa awon ogorun wolii Olorun, sugbon Elijah ko jiyan.
O lo ba Ahabu.



Nigbati awon eniyan meji naa pade, Elija koju si Ahabu pe ko ara ile Isireli jo ati gbogbo awon aadotalegberin woli eke.  Ni ibi kan ti a n pe ni ori oke Kameli, Elijah ba awon eniyan naa soro "TI OLUWA ba ni Olorun, E te le e."



Elijah ni ako maluu meji ti ati pese lati fi se ebo. Sugbon ko si ina lati fi sun un. “E pe oruko Olorun yin, emi naa o ke pe oruko OLUWA” o wi bee. “Olorun tii n dahun pelu ina, oun ni Olorun.” “O ti wii re, awon eniyan dahun.”



Lati owuro titi di asale awon woli eke pe Olorun eke won.  Won jo yi pepe naa ka, won si yaara won lobe titi eje fi n da lara won.  Sugbon ko si ina.





Nigba naa ni Elijah ko gbogbo igi sinu omi fun ebo, o si gbadura. “OLUWA, gbo temi, ki awon eniyan yii le mo pe iwo ni OLUWA Olorun...” leyin naa ina olorun bo si le. O si jo ako maluu ati gbogbo igi. Leyin na o joo gbogbo pepe okuta.

Nigbati awon eniyan rii, won kigbe, “OLUWA, oun ni Olorun.” Elijah wi pe, “E mu awon wolii Baali, mase je ki okan kii ninu won salo!” Elijah se ohun ti o ye ki oba Ahabu se lati ojo to tipe. O si pa gbogbo awon woli eke.



Nigba naa ni iranse Olorun so fun Ahabu pe ojo mbo lona. Laipe awosanma sududu, se ojo yooro ni? Leyin odun meta ati die ti oda logbara ti da.'





Leyin igba die,
oju orun su fun
awosanmo ati iji,
ojo nla siro.
Olorun ran ojo,
Olorun fihan
awon eniyan naa
pe Elijah so otito
fun won.  Olorun
fihan won pe oun
nikan ni Olorun
otito.



Nje o rope oba
Ahabu bowo fun
Olorun ati iranse re
Elijah? Rara! Lotito,
Jezebeli gbiyanju
lati pa Elijah, sugbon
o sa lo. Nigbeyin,
Ahabu ku soju ogun,
awon iranse re si ti
Jezebeli si ibi giga
ile Oba. O si subu
sori okuta, o si ku.



Kinni o sele si Elijah? Lojo kan, olorun ran keke elesin pelu ina; Elijah, eniyan Olorun ina lo si oke orun pelu aaja.

Eniyan ina (Eniyan Onina)

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Awon oba kinni,
ori iketadinlogun titi de ikodandinlogun,
Awon Oba keji ori ikeji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.